# ÀKỌMỌ̀NÀ-ÌMÚṢẸ́ṢẸ FÚN ÀWỌN ALÁWÒṢE ÈTÒ-ÌLERA

Ẹgbẹ́ tó ń Ṣiṣẹ́ lórí Àkọmọ̀nà-Ìmúṣẹ̣ṣẹ

Aáyan ògbifò isé yì ní èdè Yorûbá
(Yoruba version)

Published 2018.12.02
ssih.org/Code-of-Ethics

Supported by:

SSH
Society for Simulation in Healthcare™

# ÌFÁÁRÀ ÀTI ÌPÀJÙBÀ

## Ní ọjọ́ kẹtàlá, oṣù kìn-ín-ní (Ṣẹ́ẹ́rẹ́), ọdún okòó-lé-lẹ́gbàá-ó-dín-méjì (2018), ẹgbẹ́ àwọn aláwọ̀ṣe ètò ìlera kan kóra jọ láti orílẹ̀-èdè àgbáyé sí ibi ìpàdé kan tí ó wáyé ní ìlú Los Angeles ní California láti fẹ́nu kò lórí àkọmọ̀nà-ìmúṣẹ́ṣe tí ó jẹ́ àjọgbà fún àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ àwọ̀ṣe ètò-ìlera.

Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tó ń ṣiṣẹ́ lórí àkọmọ̀nà-ìmúṣẹ́ṣe yìí wá láti àwọn orílẹ̀-èdè jákè-jádò àwọn ìsọ̀rí mẹ́fà tí a pín gbogbo orílẹ̀-èdè àgbáyé sí, àti pé,wọ́n sì tún mú àwọn ìmọ̀ àti òye nínú iṣẹ́ àti ìṣe àgbékalẹ̀ àwọ̀ṣe lọ́wọ́. Wọ́n ṣojú àwọn adárí láti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn alábàáṣepọ̀ ẹgbẹ́ àti ilé-iṣẹ́ tí ó ní í ṣe pẹ̀lú àwọ̀ṣe.

Ṣíṣe iṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn onímọ̀ lórí ohun tó-tọ́ tàbí kò-tọ́ àti nípa fífi àkíyèsí sí àwọn mìíràn, àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ ṣe àgbékalẹ̀ tí ó jẹ mọ́ àwọn ẹ̀ka-ìmọ̀ agbátẹ̀rù àwọ̀ṣe jákè-jádò. Àwọn aláwọ̀ṣe ètò-ìlera ń ṣe àfihàn ìlépa gbòógì tí ó ṣe pàtàkì fún iṣẹ́ àwọ̀ṣe bíi: Òtítọ́-inú, Ìmọ́fẹ́fẹ́, Àpọ́nlé Aláìlákùdé, Ìmọ̀-ọ́n-ṣe, Ìfòtítọ̀jábọ̀ àti Ìlóye nípa èsì. Ètò náà ṣe àfihàn àwọn àmúyẹ tí ó ṣe pàtàkì sí ìgbáyégbádùn gbogbo igun kọ̀ọ̀kan nínú agboolé ìṣe àwọ̀ṣe tí ó jẹ́ ti ètò-ìlera, ó sì tún ń ṣe àfihàn ohun tí a jẹ́ àti ìfarajìn wa sí àwọ̀ṣe ètò-ìlera gẹ́gẹ́ bí i iṣẹ́-àkọ́ṣe.

Ẹgbẹ́ tó ń ṣiṣẹ́ lórí iṣẹ́ náà pèsè àkọmọnà-ìmúṣẹ́se Aláwọ̀ṣe ètò-ìlera fún ìtẹ́wọ́gbà àti ìlò fún àwọn ẹgbẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́, àwùjọ, àti ilé-ẹ̀kọ́, níwọ̀n ìgbà tí a bá ti ṣe àfikún tó yẹ fún àwọn ẹgbẹ́ yẹn.

**Ẹni tí Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà wà fún:** Aláwòṣe ètò-ìlera ni a ṣe àgbékalẹ̀ láti ṣe àfihàn àmúyẹ ìlépa tí ó ga jù lọ, fún gbogbo àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ àwòṣe ètò-ìlera.

**Gbígba Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà wọlé:** Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà fún gbogbo àkọmọnà-ìmúṣẹ́se, àkọmọnà-ìmúṣẹ́se yìí jẹ́ wọ̀fún. Fún ìdí èyí ó jẹ́ ìpinnu àwọn ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́, àwùjọ àti ilé-ẹ̀kọ́ láti fínnú fíndọ̀ gba àkọmọnà-ìmúṣẹ́se yìí, kí wọ́n sì tàn án kálẹ̀.

**Àfikún Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà:** Àwọn ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ àti ilé-ẹ̀kọ́ lè fẹ́ láti fẹ àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà lójú fún ìdí pàtàkì kan. Bí àpẹẹrẹ, Àjọ àwọn onímọ̀ nípa àrùn-ọpọlọ ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (America) ti gba àkọmọnà-ìmúṣẹ́se ti Àjọ Oníṣègùn-òyìnbó ti orílè.-èdè Amẹ́ríkà (America) ní àpapọ̀, bákan náà, wọ́n sì tún tẹpẹlẹ mọ́ abala àwọn ìlànà àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà, èyí tí ó ṣe pàtàkì sí ìtọ́jú àrùn-ọpọlọ.

**Àwọn Aáyan-Ògbufọ̀ fún Àkọmọnà-Ìmúṣẹ́se náà:** Ṣíṣe aáyan-ògbufọ̀ àkọmọnà-ìmúṣẹ́se jẹ́ èyí tí a fi ọwọ́ sí láti jẹ́ igi lẹ́yìn ọgbà fún òye àti àjọgbà káríayé fún àwọn àkóónú tó wà nínú rẹ̀. Àlàyé lórí ṣíṣe aáyan-ògbufọ̀ àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà ni ó wà fún àyẹ̀wò lórí ìtàkùn ayélujára.

**Ibi tí a ti lè rí Àkọmọnà-Ìmúṣẹ́se náà:** Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà wà ní ibi: ssih.Org/Code-of-Ethics.

# ORÚKỌ ÀWỌN TÓ WÀ NÍNÚ ẸGBẸ́ TÓ ṢIṢẸ́ LÓRÍ ÀKỌMỌNÀ-ÌMÚṢẸ́SE YÌÍ

Christine Park

Timothy Murphy

Zalim Balkizov

Thomaz Bittencourt Couto

Pin-Tarng Chen

John Dean

Sharon Decker

Parvati Dev

Dayna Downing

Kris Thomas Dreifuerst

Eliana Escudero Zúñiga

Valerie Fulmer

Grace Gephardt

Leslie Graham

David Grant

Edgar Israel Herrera Bastida

Leslie Hurst

Sabrina Koh

Hani Lababidi

Esther León Castelao

William Lewandowski

Jennifer McCarthy

Elaine Meyer

Geoffrey Miller

Stefan Monk

Debra Nestel

Fadekemi Oginni

Gen Ouchi

Edwin Ozawa

Gina Peña Pavez

Leona Robertson

Ismail Saiboon

Paola Santalucia

Dawn Schocken

Laura Shen

Elizabeth Sinz

Gulcihan Ulufer Sivrikaya

Cathy Smith

Mary Kay Smith

Andrew Spain

Catherine Strayhorn

Elena Tragni

Isabelle Van Herzeele

Robin Wootten

Park, C. S., Murphy, T. F., & the Code of Ethics Working Group (2018). *Healthcare Simulationist Code of Ethics*. Retrieved from http://www.ssih.org/Code-of-Ethics.

# ÀKỌMỌ̀NÀ-ÌMÚṢẸ́ṢE ÀWỌN ALÁWÒṢE ÈTÒ-ÌLERA: ÌFÁÀRÀ

Àwọn olóríjorí àti lájọlajọ tí ó nípa àti ìpín nínú àwòṣe ètò-ìlera ń ṣiṣẹ́ tọ ìṣe àìléwu, ìmúṣe tí ó gbé pẹ́ẹ̀lí, àti ètò-ìlera tí ó péye. Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se yìí yóò jẹ́ atọ́nà fún gbogbo ẹni tí ó ń ṣe àwòṣe ètò-ìlera.

Gẹ́gẹ́ bí i àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ aláwòṣe, a ṣe àkíyèsí pé ìṣe àwòṣe nípa lórí onírúurú abala ètò-ìlera. Pẹ̀lú ojúṣe yìí, a fi ara wa jìn fún àkọmọnà-ìmúṣẹ́se yìí.

Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se fún Aláwòṣe ètò-ìlera yìí ní èròǹgbà láti ṣe ìgbélárugẹ, ìfúnlókun, àti ìgbárùkùtì fún àṣà ìmúṣẹ́ṣe tó láàárìn gbogbo olóríjorí àti lájọlájọ tí ó nípa àti ìpín nínú àwòṣe ètò-ìlera. Ó ń ṣe àfihàn ìfarajìn àwọn aláwòṣe ètò-ìlera ní gbèdéke òtítọ́-inú tí ó ga jù lọ.

Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se yìí ní ìpinnu láti jẹ́ kí àwọn Aláwòṣe ètò-ìlera máa ṣe agbékalẹ̀ iṣẹ́ wọn títí dé gbèdéke tí ó péye jù lọ jákè-jádò gbogbo ayé. Ó ń mú ìtẹ̀síwájú àti ìgbélárúgẹ bá àwọn àmúyẹ àti ìṣe pàtàkì tí Ètò Ìgbèrú Àpapọ̀ àwọn orílẹ̀-èdè àti àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ẹgbẹ́ mìíràn là kalẹ̀.

# ÀKỌMỌNÀ-ÌMÚṢẸ́SE FÚN ÀWỌN ALÁWÒṢE ÈTÒ-ÌLERA: ÀWỌN ÀMÚYẸ̀

## I. Òtítọ́-inú

Àwọn Aláwòṣe Ètò-ìlera yóò ṣe àmúlò òtítọ́-inú ní gbèdéke tí ó ga jù lọ pẹ̀lú àìṣèèrú, ìṣòtítọ́, ìṣòdodo, àti ìdájọ́ nínú gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó bá jẹ́ ti iṣẹ́ wọn. Wọn yóò:

- Ṣe àpọ́nlé àti ìtẹ̀ríba fún ẹ̀kọ́ ìwà rere tí ó jẹ́ ti agbègbè ilé-iṣẹ́
- Pèsè, gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ, àfihàn àwọn iṣẹ́ tí wọ́n yàwòrán rẹ̀ pẹ̀lú èrò-ọkàn, gbèdéke, àtúnṣe àti ìṣòro tí ó jẹ́ ti àwòṣe ni wọn yóò ṣe.
- Fí ohun tí ó jẹ́ ti àmúṣe iṣẹ́ àti ọnà àwòṣe hàn gbangba nípa ẹ̀rí tí ó bá wà ní àrọ́wọ́tó.
- Ṣe iṣẹ́ láti fòpin sí ìpalára àìnídìí tí ó lè dé bá ènìyàn, ẹranko àti agbègbè.
- Bọ̀wọ̀ fún ẹ̀tọ́ ìkọ̀kọ̀ àwọn olóríjorí àti lájọlájọ, àti ìdìmú ṣinṣin àwọn àkójọpọ̀-fáyẹ̀wò tí ó jẹ́ àṣírí àti àbáyọrí wọn gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ.
- Ṣe àpọ́nlé àti ìjẹ́rìí gbogbo ẹ̀tọ́ olóye àti ohun-ìní láti ṣe ẹ̀tọ́ níbi tí ó ti yẹ.

## II. Ìmọ́féfé

Àwọn Aláwòṣe ètò-ìlera yóò ṣe gbogbo iṣẹ́ àwòṣe ètò-ìlera ní ọ̀nà tí ó ń ṣe ìgbèrú ìmọ́féfé àti ìsọdimímọ̀ nínú àwòrán, ọ̀nà-ìbánisọ̀rọ̀, àti ètò ìpinnu ṣíṣe. Wọn yóò:

- Fọwọ́ sí àtigba àwọn gbèdéke tí ó wà nínú àkọsílẹ̀-fún-ìpamọ́, ìtúpalẹ̀, ìyàwòrán, ìgbèrú, ìṣẹ̀dá, àti àyẹ̀wò iṣẹ́ àwòṣe.
- Ṣe àfihàn iṣẹ́kíṣẹ́ tí ó lè lòdì sí ẹwù ẹnikẹ́ni lọ́nà ẹ̀rọ tàbí ní sàn-án.
- Fi ọ̀rọ̀ nípa ẹ̀dá àti èròǹgbà iṣẹ́ àwòṣe hàn pẹ̀lú iṣẹ́-ìwádìí.
- Lòdì sí iṣẹ́ àwòṣe tí ó ní í ṣe pẹ̀lú àgàbàgebè, kí á rí i pé àgàbàgebè dínkù tó bí ó ṣe lè ṣeé ṣe, àti pé, tí kò sì ní fífi ewu pa mọ́ tàbí níni ìpinnu láti pa ènìyàn lára tàbí láti fi ìyà jẹ ẹnì kan.

## III. Àpọ́nlé Alâìlákùdé

Àwọn Aláwòṣe ètò-ìlera yóò ṣe àpọ́nlé àwọn ẹ̀tọ́, ọlá, àti iyì ènìyàn gbogbo. Wọn yóò ṣe ìbákẹ́dùn àti ìyọ́nú láti ṣe àtìlẹyìn ojú-rere àti àìjẹ́-ẹni-burúkú pẹ̀lú àwọn tí ó nípa àti ìpín nínú iṣẹ́ àwòṣe. Wọn yóò:

- Bọ̀wọ̀ fún ìmọ̀, ọ̀gbọ́ndàá, àmúyẹ àti àìlókun àwọn ṣẹ̀ṣẹ̀dé àti akẹgbẹ́ wọn.
- Fetí sí ojú-àmúwayé àwọn ẹlòmíràn, wíwá ọ̀nà láti gbọ́ wọn ní àgbọ́yé.
- Ṣe àfihàn ìwà ọmọnìyàn, bọ̀wọ̀ fún ìyàtọ̀, àti àjọṣepọ̀, yíyẹra fún ìwà àìtọ́.
- Ìgbèrú ààbò àti mímú àdínkù bá ewu àfojúrí àti àfọ̀kàn-rò.

## IV. Ìmọ̀-ọ́n-ṣe

Àwọn Aláwòṣe ètò-ìlera yóò hùwà lọ́nà tí ó ní ìgbéró gbèdéke akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ó ṣo do sínú àwòṣe ètò-ìlera. Wọn yóò:

- Ṣe àmúlò ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú iṣẹ́ àmúṣe àti ìwà akọ́ṣẹ́mọṣẹ́
- Ṣe àgbéjáde ìgbèrú aláìlódiwọ̀n tí kì í dúrótí ó jẹ́ ti ara-ẹni àti ti ìkọ́ṣẹ́mọṣẹ́
- Ṣe ìkóríyá àti ìmúgbòòrò fún àwọn akẹgbẹ́ wa àti àwọn tí wọ́n sẹ̀ṣẹ̀ wọlé sí iṣẹ́ àwòṣe ètò-ìlera.
- •e ètò àǹfààní fún ìmúdàgbà iṣẹ́ àwòṣe ètò-ìlera.

## V. Ìfòtítọ́-jábọ̀

Àwọn Aláwòṣe ètò-ìlera yóò fi òtítọ́ jábọ̀ ìpinnu àti ìgbésẹ̀ wọn láti kógo já nínú àwọn ojúṣe àti iṣẹ́ wọn. Wọn yóò:

- Máa wá ṣe àbọ̀ iṣẹ́ ṣíṣe bẹ́ẹ̀ ni wọn ó máa ṣe àpérò àti àtúnṣe láìdẹ́kun wọn.
- Jọ̀wọ́ ara wọn fún àyẹ̀wò tí ó jẹ́ ti iṣẹ́ tí wọ́n yàn láàyò nígbà tí ó bá yẹ.
- Jẹ́ àwòkọ́ṣe fún ìṣe tó tọ́
- Ṣe àgbéjáde ìwà akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ó jẹ́ èrè fún àwòṣe ètò-ìlera agboolé, agbaniṣíṣẹ́ àti ara-ẹni.
- Ṣe àfihàn àti ìkéde fún oríṣiríṣi igun lórí ohun tí ó jẹ elewu, aláìníwà rere, tàbí ìwà àìkójú-òṣùwọ̀n lẹ́nu iṣẹ́.
- Ya àwòrán àti ìlò àwòṣe ní ọ̀nà tí ó ń ṣe àmúlò àwọn èròjà tí ó wà ní àrọ́wọ́tó pẹ̀lú ọgbọ́n.
- Ṣe àmójútó tí ó dán mọ́rán nípa àtunbọ̀tán tí a fojú sùn, kì í ṣe èyí nìkan, ṣùgbọ́n kíkógìiírí mọ́ àwọn àtunbọ̀tán tí a kò retí náà tí ó jẹ́ mọ́ iṣẹ́ àwòṣe.

## VI. Ìlóye nípa Èsì

Àwọn Aláwòṣe Ètò-ìlera yóò ṣe iṣẹ́ sìn láti ṣe àtìlẹyìn fún ìgbèrú ojúlówó iṣẹ́ àti ẹ̀ka ètò-ìlera. Àwọn èsì jẹ́ ara àkóónú gbogbo abala ọ̀nà àwòṣe ètò-ìlera, àti pé, wọn kì í ṣe àṣàdànù nínú àṣeparí iṣẹ́. Wọn yóò:

- Ṣe àmúlò àwòṣe ètò-ìlera lọ́nà tí ó ṣeé gbé ara lé tí ó sì tún lérè, èyí tí yóò wà ní ìbámu pẹ̀lú ìmòye gbèdéke ti ìṣe yìí.
- Kópa nínú ìgbèrú tí ó jẹ́ ojúlówó láìsinmi.
- Ṣe ìṣẹ̀dá àti ìgbéléwọ̀n àwọn ipa àṣeyọrí jákè-jádò lórí òṣùwọ̀n, pẹ̀lú ìṣe àwòṣe àmúṣe ọmọnìyàn, ìgbèrú ẹlẹ́kajẹ̀ka, àti àwọn èsì ipa tí wọ́n ni lórí àwọn olùgbàtọ́jú.
- Ṣe ìgbàwọlé àti ìfìdímúlẹ̀ àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà jákè-jádò àwòṣe ètò-ìlera àti àṣà lájọlájọ.
- Ṣe àmúlò àkọmọnà-ìmúṣẹ́se náà láti ṣe àfihàn ìmúṣẹ́ṣe-tó nínú àwọn abala ìmọ̀ tó jẹ mọ́ wa.
- Ṣe ìmúgbòòrò ìmọ̀ àwùjọ lórí àwòṣe ètò-ìlera nípa ṣíṣe àtìlẹyìn fún wíwà ní àrọ́wọ́tó àti ìpínkiri ìmọ̀ àti ìrírí.

Àkọmọnà-ìmúṣẹ́se fúna wọn Aláwòṣe Ètò-ìlera ń ṣe àfihàn ìlépa gbòógì tí ó ṣe pàtàkì fún iṣẹ́ àwòṣe:

**I.** **Òtítọ́-inú**

**II.** **Ìmọ́féfé**

**III.** **Àpọ́nlé Aláìlákùdé**

**IV.** **Ìmọ̀-ọ́n-ṣe**

**V.** **Ìfòtítọ́-jábọ̀**

**VI.** **Ìlóye nípa Èsì**

**Yoruba version translated by:**

- **Fadekemi Oginni**
- **Salawu Akeem Segun**
- **Joseph Phillip Ayobami**

*Translations of the Healthcare Simulationist Code of Ethics are prepared by volunteer translators. No liability is assumed by SSH or the code of ethics authors for any errors, omissions, or ambiguities in the translations provided. Any person or entity that relies on translated content does so at their own risk. Neither SSH nor the code of ethics authors shall be liable for any losses caused by reliance on the accuracy, reliability, or timeliness of translated information.*

*Supported by:*

SSH

Society for Simulation in Healthcare™